Bibeli fun awon omode



# Adari tempili be Jesu wo

Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Byron Unger; Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: M. Maillot; Sarah S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Nigba ti Jesu lo si inu Tempili lojo kan, O ri awon eniyan ti ko bu ola fun ile Olorun.  Won n ta eranko, won si n paaro owo ninu Tempili!



Jesu fi okun se pasan, O si le awon onisowo naa jade kuro ninu Tempili.  O pase pe, “E gbe awon nnkan wonyii kuro.  E ma so ile Baba mi di ibi itaja” Jesu feran ile Baba re.





Awon aladari ni
ki Jesu fi ami
han pe oun ni ase
lati fo Tempili
mo. Jesu da won
lohun pe, "E wo
Tempili yii lule,
maa si gbe e
dide ni ijo meta."
Ko see se! Awon
Juu lo to bii
ogoji-odun o le
mefa lati ko
Tempili yi.

Sugbon Jesu n so nipa ara re. Ago ara Re ni ibugbe Olorunbi Tempili ti je ile Olorun fun awon Juu. Bi o ti je pe Jesu yi o ku lori agbelebu, o mo pe Olorun yoo gbe oun dide ni ojo keta.





Ni oru, okan lara awon adari Tempili lo be Jesu wo. O mo pe nipa awon ise iyanu re wipe Olorun ni o ran Jesu. Nikodemu to Jesu wa lati ko nipa Olorun si.



Jesu so fun Nikodemu pe eniyan gbodo di atunbi lati wo ijoba Olorun.  Ko ye Nikodemu.  Bawo ni agbalagba yoo se tun pada di omode? Yato fun eyi o je olugbesin lori.  Se iyen ko to?



Jesu se alaye
fun bayi pe, “Eni
ti a ti ipa emi bi
ti emi ni.” “Emi
Olorun dabi
afefe. Eniyan
ko lee ri afefe.
Won kan ma nri
ohun ti afefe n
se ni.”



Jesu ran Nikodemu leti bi awon omo Israeli se kunsi Mose nigba atijo. Won nkigbe "A ko ni ounje, ko si omi, a si korira ounje ti Olorun fun wa."

Ese awon eniyan naa mu ki Olorun binu si won. O ranawon ejo amubina saarin won. Ejo bu awon eniyan naa san. Opo ninu won si ku.





Won ba bere sii bebe pe, "A ti se. Gbadura pe ki Olorun mu awon ejo yii kuro." Mose gbadura fun won. Sugbon Olorun ko mu awon ejo naa kuro.



Olorun so fun Mose ki o ro ejo amubina ki o sigbe ko ori igi.  Olorun seleri fun won wipe, "Enikeni ti ejo ba bu san ti o ba wo eyi ti a gbe ko si ori igi yoo ye".  Mose se ejo ideawon ti o wo si ye.



Jesu so fun Nikodemu pe
a gbodo gbe omo eniyan
soke gege bi ejo ide.
Jesu n soro iku
ori igi agbelebu
ti yo ku fun
awon elese.



Jesu wi pe "Olorun fe araye to bee ge ti o fi omo bibi re kan soso fun nii pe enikeni ti o ba gbagbo ninu re ki yoo parun sugbon yio ni iye ainipekun."



Eyi tumo si pe
enikeni ti o ba gba
Jesu gbo, a ti bi
i sinu ebi
Olorun.

Boya Nikodemi ko di omo eyin Jesu ni our ojo yi. Sugbon leyin odun die, Nikodemu fihan pe oun feran Jesu, o si gba a gbo iranlowo ti o se lori isinku omo Olorun ti a kan mo agbelebu.



Leyin eyi Jesu ati awon omo eyin re rin irinajo lo si iha Ariwa. Awon miiran naa ni lati gbo nipa ijoba Olorun ki won si ni anfani lati gbagbo ninu Jesu ti Nazareti, Omo Olorun.



Adari tempili be Jesu wo

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Johanu ori keji ati keta,
Numeri ori Kookanlelogun

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.